# ADURA DAFIDI

## Orin Dafidi 72:1-19

## ẸKỌ 248 -- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Olubukún li OLUWA Ọlọrun, Ọlọrun Israẹli, ẹnikanṣoṣo ti nṣe ohun iyanu" (Orin Dafidi 72:18).**

**I Ijọba Ainipẹkun**

1 Onipsalmu fẹ ki a fi ododo ati idajọ Ọlọrun fun Ọmọ Ọba, Orin Dafidi 72:1; Isaiah 59:16, 17; Jeremiah 23:5, 6
2 Ọba yoo ṣe idajọ awọn eniyan pẹlu ododo ati ẹtọ́, Orin Dafidi 72:2-4; Isaiah 11:2-5; 9:7; 32:1
3 Ijọba yii ki yoo nipẹkun, Orin Dafidi 72:5-7; Daniẹli 2:44; Luku 1:32, 33; Mika 4:7
4 Ijọba Rẹ yoo bori ohun gbogbo, Orin Dafidi 72:8-11; 59:13; 103:19; Daniẹli 7:14; Ifihan 21:24-26
5 Ọba yoo gbọ́ yoo si dahun igbe awọn alaini, talaka ati awọn ti a n nilara, Orin Dafidi 72:12-14; Isaiah 2:4; Hosea 2:18; Mika 4:3, 4; Isaiah 60:1-22
6 A o gbe Ọba naa ga, a o si bu ọlá fun Un, Orin Dafidi 72:15-20; Isaiah 2:1-3; Mika 4:1, 2; Luku 1:32, 33; Filippi 2:9, 11; Ifihan 19:12, 16

## ALAYÉ

### Ọmọ Ọba

Adura Dafidi ti a kọ silẹ fun wa ninu Bibeli ninu Orin Dafidi kejilelaadọrin tayọ adura. Ijẹwọ igbagbọ ati asọtẹlẹ nipa Messia ni ọna ti o daju ni. Oye yé Dafidi nipa eto igbala Ọlọrun; bi imọ̀ ati oye Dafidi ti pọ to nipa Ijọba Ọlọrun si fi ara hàn fun ni ninu adura yii.

O hàn daju pé adura Dafidi pée ki idajọ ati ododo Ọlọrun ki o le jẹ ti Ọmọ Ọba ki i ṣe ni pato fun Sọlomọni ọmọ rẹ̀. Ijọba Sọlomọni kún fun alaafia ati ibukun ti kò lẹgbẹ ninu itan igbesi-aye awọn Ọmọ Israẹli ṣaaju ati lẹyin eyi. Sibẹsibẹ ijọba Sọlomọni kò to nnkan lara Ijọba ti Ẹmi Mimọ n tọka si lati ẹnu Dafidi. Dafidi ki i ṣe ope nipa Olugbala ati Ọba rẹ̀ ti n bọ wa, kò si ṣe aibikita si alaafia ati ọpọ ibukún ti yoo jẹ apa kan Ijọba ti a o gbe kalẹ nigbooṣe ninu aye. Adura rẹ̀ jẹ eyi ti o kún fun imisi Ọlọrun ti o rú ifẹ rẹ̀ soke lati beere pe ki Ijọba naa tete de.

Dafidi nikan kọ ni ẹni ti Ọlọrun fi diẹ ninu ogo Ijọba Ọmọ Rẹ̀ hàn. Isaiah sọ asọtẹlẹ nipa Jesu Kristi ati Ijọba Rẹ: "A bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa: ijọba yio si wà li ejika rẹ̀: a o si ma pe orukọ rẹ̀ ni Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ-Alade Alafia" (Isaiah 9:6).

A ti yàn Kristi lati jọba lati ipilẹṣẹ aye. (Wo I Peteru 1:20). Onipsalmu wi pe, "Lati igba atijọ li a ti fi idi itẹ́ rẹ kalẹ, ati aiye-raiye ni Iwọ" (Orin Dafidi 93:2).

Johannu Apọsteli ni erekuṣu Patmo, ri Ẹni ti yoo jọba, o si gbọ ti ọpọlọpọ eniyan wi pe: "Yiyẹ li Ọdọ-agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara, ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ogo, ati ibukún. Gbogbo ẹda ti o si mbẹ li ọrun, ati lori ilẹ aiye, ati nisalẹ ilẹ, ati irú awọn ti mbẹ ninu okun, ati gbogbo awọn ti mbẹ ninu wọn, ni mo gbọ́ ti nwipe, Ki a fi ibukún ati ọlá, ati ogo, ati agbara, fun Ẹniti o joko lori itẹ́ ati fun Ọdọ-Agutan na lai ati lailai" (Ifihan 5:12, 13).

### Ijọba Ododo

Nipa ẹtọ, Jesu Kristi ni Alakoso Ijọba yi, Oun yoo si jọba ni ododo. A kà ni ibi pupọ ninu Iwe Mimọ nipa ododo ati ẹwa idajọ Ọba naa. "Olododo ni iwọ, OLUWA, ati diduro-ṣinṣin ni idajọ rẹ" (Orin Dafidi 119:137); "Ododo rẹ ododo lailai ni" (Orin Dafidi 119:142); ati "Ododo ati idajọ ni ibujoko itẹ́ rẹ̀" (Orin Dafidi 97:2). Ododo ni aṣẹ Rẹ, idajọ ati ọrọ Rẹ (Wo Orin Dafidi 119:172; 19:9; 119:123). "Olododo li OLUWA li ọ̀na rẹ̀ gbogbo, ati alãnu ni iṣẹ rẹ̀ gbogbo" (Orin Dafidi 145:17). A tun kà pe, "Yio fi ododo ṣe idajọ aiye, ati ti enia ni yio fi otitọ rẹ̀ ṣe" (Orin Dafidi 96:13). Iba diẹ ninu awọn ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun ti o sọ nipa ijọba ododo Ọba naa ni awọn wọnyi.

**Ilẹ Ẹwa**

Woli Isaiah sọ ni iwọn iba ọrọ diẹ ṣoki gẹgẹ bi Ijọba Ọlọrun ninu aye yii yoo ti gbilẹ to. “Ijọba yio bi si i, alafia ki yio ni ipẹkun” (Isaiah 9:7). A kà ninu ori ẹkọ wa yii pe, “On o rọ̀ si ilẹ bi òjo si ori koriko irẹ́-mọlẹ: bi ọwọ òjo ti o rin ilẹ. Li ọjọ rẹ̀ li awọn olododo yio gbilẹ: ati ọ̀pọlọpọ alafia niwọn bi òṣupa yio ti pẹ to.” Awọn ẹsẹ miiran ti o fara jọ ẹkọ wa wá si iranti. “On o si ṣe idajọ lãrin ọ̀pọlọpọ enia, yio si bá alagbara orilẹ-ède rére wi; nwọn o si fi idà wọn rọ ọbẹ -- plau, ati ọ̀kọ wọn rọ dojé: orilẹ-ède kì yio gbe idà si orilẹ-ède, bẽni nwọn kì yio kọ́ ogun jijà mọ. Ṣugbọn nwọn o joko olukuluku labẹ ajara rẹ̀ ati labẹ igi ọpọtọ rẹ̀; ẹnikan kì yio si daiya fò wọn” (Mika 4:3, 4).

Ẹsẹ wura miiran ninu Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa nipa alaafia Ijọba Ọlọrun ninu aye: “Nwọn o si kọ ile, nwọn o si gbe inu wọn; nwọn o si gbìn ọgba àjara, nwọn o si jẹ eso wọn. Nwọn kì yio kọ ile fun ẹlomiran igbe, nwọn ki yio gbìn fun ẹlomiran ijẹ; nitori gẹgẹ bi ọjọ igi li ọjọ awọn enia mi ri, awọn ayanfẹ mi yio si jìfà iṣẹ ọwọ́ wọn. Nwọn ki yio ṣiṣẹ lasan, nwọn ki yio bimọ fun wahala: nitori awọn ni iru alabukun OLUWA ati iru-ọmọ wọn pẹlu wọn. Yio si ṣe, pe, ki nwọn ki o to pè, emi o dahùn; ati bi nwọn ba ti nsọ̀rọ lọwọ, emi o gbọ́” (Isaiah 65:21-24).

**Ijọba gbogbo Agbaye**

Nigba ijọba Sọlomọni orilẹ-ède Israẹli di olokiki laaarin awọn orilẹ-ède. Awọn orilẹ-ède aye a maa mu ọja wọn wa si ilẹ Israẹli, wọn a si maa mu ẹbun iyebiye wa fun Sọlomọni ọba ni imoore ati iyin fun ọgbọ́n rẹ̀. Ayaba Ṣeba wa lati ọna jijin lati bẹ Sọlomọni wo; o si sọ bayi nipa aafin ati awọn iranṣẹ rẹ̀ ati nipa ọna ijọsin rẹ̀ pé, “Kiyesi i, a kò rò idaji titobi ọgbọ́n rẹ fun mi; nitori ti iwọ kọja òkiki ti mo ti gbọ́. Ibukún ni fun awọn enia rẹ, ibukún si ni fun awọn iranṣẹ rẹ wọnyi, ti nduro nigbagbogbo niwaju rẹ, ti o si ngbọ́ ọgbọ́n rẹ” (II Kronika 9:6, 7).

Eyi jẹ apẹẹrẹ bi awọn ọba aye yoo ti maa wa lati sin ati lati wári fun Ọmọ Ọba nigba Ijọba Rẹ̀. A ka ninu ori ẹkọ wa pe “Awọn ọba Tarṣiṣi, ati ti awọn erekuṣu yio mu ọrẹ wá; awọn ọba Ṣeba ati ti Seba yio mu ẹ̀bun wá. Nitõtọ, gbogbo awọn ọba ni yio wolẹ niwaju rẹ̀: gbogbo awọn orilẹ-ède ni yio ma sin i.”

Ijọba Sọlomọni bori gbogbo awọn orilẹ-ède ti o wà nigba aye rẹ̀, ṣugbọn Ijọba Ọlọrun lori ilẹ aye yoo de gbogbo opin aye. Ọpa irin ni Kristi yoo fi ṣe akoso; awọn keferi yoo jẹ ini Rẹ̀, gbogbo opin aye yoo si jẹ ti Rẹ̀ ni ini (Ka Orin Dafidi 2:8, 9).

A fi iran ikẹyin ọjọ hàn Daniẹli, o si kọ akọsilẹ yii pe, “Mo ri ni iran oru, si kiyesi i, ẹnikan bi Ọmọ enia wá pẹlu awọsanma ọrun, o si wá sọdọ Ẹni-àgba ọjọ na, nwọn si mu u sunmọ iwaju rẹ̀. A si fi agbara Ijọba fun u, ati ogo, ati ijọba, ki gbogbo enia, ati orilẹ, ati ède, ki o le ma sin i; agbara ijọba rẹ̀ si jẹ agbara ijọba ainipẹkun, eyiti a ki yio rekọja, ati ijọba rẹ̀, eyiti a ki yio le parun” (Daniẹli 7:13, 14).

**Ijuba Gbogbo Aye**

“Nitori tẹmpili rẹ ni Jerusalẹmu li awọn ọba yio ma mu ọrẹ fun ọ wá” (Orin Dafidi 68:29). Ori ẹkọ wa sọ bayii, “On li a o si fi wura Ṣeba fun” (Orin Dafidi 72:15). Asọtẹlẹ Isaiah sọ nipa awọn ti yoo wa lati juba Ọba naa pe, “Awọn Keferi yio wá si imọlẹ rẹ, ati awọn ọba si titàn yiyọ rẹ.” “Ọ̀pọlọpọ rakunmi yio bò ọ mọlẹ, awọn ọmọ rakunmi Midiani on Ẹfa; gbogbo wọn o wá lati Ṣeba: nwọn o mu wura ati turari wá; nwọn o fi iyìn OLUWA hàn sode. A o ṣà gbogbo ọwọ́-ẹran Kedari jọ sọdọ rẹ, awọn àgbo Nebaioti yio ṣe iranṣẹ fun ọ; nwọn o goke wá si pẹpẹ mi pẹlu itẹwọgba, emi o si ṣe ile ogo mi li ogo” (Isaiah 60:3, 6, 7).

**Orukọ Ayeraye**

Ọpọlọpọ orilẹ-ède ni o ti parẹ́, ogunlọgọ eniyan ni o si ti di ẹni igbagbe ninu iboji. Aimoye awọn ọba ati ijoye ni o ti fi ilẹ bora ti ẹnikẹni kò tun ri wọn tabi gbọ́ nipa wọn mọ. Orukọ wọn ti di igbagbe; iba diẹ ni a kọ silẹ nipa wọn ninu iwe itan.

Ṣugbọn Ọba ti yoo jẹ lori gbogbo ilẹ aye ni orukọ kan ti a kò ti i gbagbe, ti a kò si ni gbagbe titi aye ailopin. Bi ọdun ti n yi lu ọdun ni ogo orukọ Rẹ̀ n tan siwaju ati siwaju. Abawọn kan kò ba le orukọ Rẹ̀ ri lati ipilẹṣẹ, ogo rẹ̀ yoo si maa tàn titi lae. “Orukọ rẹ̀ yio wà titi lai: orukọ rẹ̀ yio ma gbilẹ niwọn bi ôrun yio ti pẹ to: nwọn o si ma bukún u fun ara wọn nipasẹ rẹ̀; gbogbo awọn orilẹ-ède ni yio ma pè e li alabukúnfun” (Orin Dafidi 72:17).

**AWỌN IBEERE**

1 Ta ni Ọmọ Ọba?
2 Bawo ni a ṣe mọ̀ pe ki i ṣe Sọlomọni ni Dafidi n gbadura fun ninu Psalmu yii?
3 Ki ni yoo jẹ aalà Ijọba yii?
4 Ṣe apejuwe iru ijọba ti yoo gbilẹ nigba Ijọba Ọmọ Ọba naa.
5 Ki ni ṣe ti gbogbo awọn ọba miiran ati orilẹ-ède yoo maa juba Ọba yii?
6 Ki ni ṣe ti a kì yoo gbagbe orukọ Ọba yii?